shineyoureye

# Sabi

## The First Truly Pan-African Toolkit for Seniors



## Yoruba

*Also available in English, Pidgin, Igbo, Hausa, French, Swahili and Zulu*

*Powered by*
cybersafe.
FOUNDATION

# Ìdáàbòbò Lórí Ìkànnì Àjọlò




## Awọn idi Lati seto 2FA

- Ọfẹ ni, ó sì rọrùn láti lò
- Ó máa ń jẹ kí èèyàn ní ìdáàbòbò tó túbọ lágbára. Kódà tí wọn bá jí ọrọ ìwọlé àti orúkọ rẹ, kò ní séwu.
- Ó máa ń dáàbò bo gbogbo ìsọfúnni rẹ, kò sì nì jẹ kí àwọn onígbájúẹ (ọmọ yahoo) jí ìsọfúnni rẹ tàbí kí wọn máa fi orúkọ rẹ díbọn.
- Ó máa ń jẹ kó ṣòro fún àwọn ọmọ yahoo láti rí okan jí lọw

## Ohun Mẹta Tó o Nílò Láti Lè Lo 2FA




## Kí ni 2-Factor Authentication (Ìdáàbòbò onílọpo méjì)

“Ṣé ìwọ ni lóòótọ?” Ìbéèrè tí Two-Factor Authentication máa ń bèèrè nìyẹn nígbàkigbà tó o bá fẹ wọlé sórí àwọn àkátì rẹ lórí ìkànnì.

Two-Factor Authentication màa ń pèsè ètò ìdáàbòbò onílọpo mèjì, kì í jẹ kéèyàn lo orúkọ àti ọrọ ìwọlé lásán, ó tún máa ń bèèrè kóòdù mîì tó o bá ń gbìyànjú láti wọlé. Orí fóònù rẹ ni wọn máa fi kóòdù yìí rànsẹ sí, tàbí kó jẹ lórí email tàbí lórí ohun èlò ìdánimọ (authentication app), èyíkéyìì tò o bá ti yàn sáájú.

Gẹgẹ bí irin ojú fèrèsé àti ilẹkùn (burglar proof) se máa ń dèna àwọn olè láti má se fọlé kó ni lẹrù, bẹẹ náà ni 2FA se máa ń dèna àwọn ọdaràn orí íntánẹẹtì (àwọn oníjìbìtì) láti má se jí àwọn ìsọfúnni rẹ lórí íkánní tàbí lo gbájúẹ fún ẹ.

**Sé o ti gbọ nípa ohun èlò ìdánimọ (authentication app)**

Ohun èlò yìí máa ń fún èèyàn ní kóòdù tó máa jẹ kèèyàn lè lo ìdábòòbò onílọọpo méjì. App yìí kò ní ohunkóhun ṣe pẹlú nọńbà tẹlifóònù rẹ. Ìdí nìyẹn tí ọpọ èèyàn fi máa ń dámọràn ẹ fún ṣíṣètò 2FA. Àpẹẹrẹ kan ni Google Authenticator (o lè wà á jáde lórí Play Store àti iOS App Store).

Jẹ́ kí n Sàlàyé bó o se lè Sètò 2FA lórí WhatsApp àti Facebook.

**Àkíyèsì:** O lè lo 2FA lórí gbogbo àkáǹtì rẹ lórí ìkànnì àjọlò àti lórí app báǹkì rẹ.




**O lè lo 2FA níbikíbi**

## Lórí WhatsApp

- Tan WhatsApp lórí fóònù ẹ
- Tẹ àmì kékerè mẹta tó wà lápá ọtún lókè
- Tẹ Settings
- Tẹ Account
- Tẹ Two-step verification
- Tẹ Enable
- Fi nọ́ńbà àṣírí tó o yàn sí i
- Fi nọ́ńbà àṣírí sí i lẹ́ẹkan sí i
- Tẹ Next
- Fi àdírẹ́sì email rẹ sí i
- Tún fi àdírẹ́sì email rẹ sí i lẹ́ẹkan sí i
- Tẹ Save
- Tẹ Done

## Awọn igbesẹ lati tan 2FA lori Facebook

- ọlé sórí ìkànnì Facebook
- Lọ sí Settings and Privacy
- Tan Settings
- Lọ sí ìsàlẹ, kó o sì tẹ Security and Login
- Tẹ Use two-factor authentication
- Yan Text message (SMS), kó o sì tẹ Continue
- Tẹ nọ́ńbà fóònù rẹ sí i, kó o sì tẹ Confirm
- Tẹ ọrọ àṣírí láti fi dá ẹ mọ
- Tẹ kóòdù tí wọn fi ránṣẹ́ sí ẹ
- Wà á rí abala kan tó máa fi hàn pé o ti ṣe tán

## Ohun tó yẹ kó o ṣe tí fóònù rẹ bá sọnù




Ìnira ńlá ló máa ń jẹ tèèyàn bá sọ fóònù nù, pàápàá tó bá jẹ pé èèyàn tún pàdánù owó tí ò rọrùn láti ṣiṣẹ fún. Báwo nìyẹn ṣe lè ṣẹlẹ? Ìṣètò báǹkì lórí fóònù ni. (mobile banking)

Ó fẹrẹẹ jẹ pé gbogbo èèyàn ló ń lo mobile banking nípa lílo nọ́ńbà USSD (kóòdù tí kò gùn), tàbí nípa lílo ohun èlò orí fóònù (mobile app) láti fi sanwó tàbí gbowó ní báńkì.

USSD (quick code) jẹ ọnà ìgbàbànisọrọ kan tí àwọn tó ń lo ẹrọ ìbánisọrọ àti àwọn onībàárà máa ń lò láti fi ìsọfúnni ránṣẹ sí àwọn ilé iṣẹ tó ń pèsè ètò ìṣiṣẹ fóònù (network service providers) tàbí àwọn ilé iṣẹ tó ń pèsè ètò ìfowópamọ lórí ẹrọ (mobile financial services). Tó o bá tẹ nọ́ńbà tó bẹrẹ pẹlú * tó sì parí pẹlú #, USSD lò ń lò yẹn.

Ọnà méjì ló wà tó o lè gbà dènà àdánù owó tí wọn bá jí fóònù rẹ,
1.Ti káàdì SIM rẹ; rí i dájú pé o gbé ìgbésẹ yìí kí fóònù ẹ t ́o sọnù.
2.Sọ fún báǹkì ẹ kí wọn ti àkáǹtì ẹ pa; o gbọdọ ṣe èyí ní kété lẹ̀yìn tó o bá mọ pé fóònù ẹ ti sọnù.

## Bó o ṣe lè dáàbò bo káàdì SIM rẹ

### Fóònu iOS

- Lọ sí Settings lórí fóònù iOS.
- Tẹ Mobile Data.
- Wá SIM PIN, kó o sì tẹ ẹ
- Tan SIM PIN.
- Tẹ kóòdù (PIN) tó o fí ń ti SIM ẹ ní lọọlọọ sí i, tàbí kó o lo èyí tá a dàbáà.
- Tẹ Change PIN
- Tẹ PIN táa dábàá lẹẹkan sí i.
- Tẹ PIN tuntun láti dáàbò bo káàdì SIM rẹ
- Tẹ Done
- Rí i dájú pé o rántí PIN rẹ!

### Fóònu Android

- Lọ sí Settings, kó o sì yan Security.
- Tó bá jẹ pé fóònù tó ní SIM méjì lò ń lò, yan SIM tó o fẹ dáàbò bò.
- Ṣètò ìdáàbòbò káàdì SIM
- Tẹ PIN tó bá SIM wá (default PIN)
- Tẹ Change SIM PIN.
- Tẹ PIN àtijọ sí i, kó o sì tẹ OK.
- Tẹ PIN tuntun sí i láti dáàbò bo káàdì SIM rẹ.
- Tẹ PIN tuntun (nọ́ńbà mẹrin) náà lẹẹkan sí i.
- Tẹ OK, kó o sì kúrò ní abala yẹn.

Àwọn PIN tó máa bá SIM wá (Default PIN):
**MTN = 00000, Airtel = 1234, Glo = 0000 àti 9mobile = 0000**

## Bi O Se Le Dena Jiji Owo Inu Akanti Re

| Banki | Igbese |
|---|---|
| Access Bank | Te *901*911# latori foonu eyikeyii tabi ko o pe +23412802500 |
| EcoBank | Te *326*911*1*nonba foonu re# latori foonu eyikeyii tabi ko o pe 0700 500 0000 |
| Fidelity Bank | Te *770*nonba foonu re# latori foonu eyikeyii |
| First Bank | Pe 07080625000 latori foonu eyikeyii |
| First City Monument Bank | Te *329*911# latori foonu eyikyii tabi ko o pe 0700 329 0000 |
| Guarantee Trust Bank | Te *737*51*74# latori foonu eyikeyii |
| Heritage Bank | Te *745# ko o si te le awon itoni ti won ba fun e |
| Keystone Bank | Te *7111*911# latori foonu eyikeyii tabi ko o pe 23470020003000 |
| Polaris Bank | Pe 08069880000 latori foonu eyikeyii |
| Stanbic IBTC | Pe 01-422-2222 latori foonu eyikeyii |
| Standard Chartered Bank | Te *977*991# latori foonu eyikeyii tabi ko o pe 012704611 |
| Sterling Bank | Te *822*911# latori foonu eyikeyii tabi ko o pe 0700 7837 5464 |
| United Bank of Africa (UBA) | Te *919*9# latori foonu eyikeyii tabi ko o pe 0700 225 5822 |
| Union Bank | Te *826*6*nonba foonu re# latori nonba eyikeyii |
| Unity Bank | Te *7799*9*nonba foonu# latori foonu eyikeyii |
| Wema Bank | Te *945*911# latori foonu eyikeyii |
| Zenith Bank | Te *966*911# latori foonu eyikeyii |

## Àwọn orúkọ kúkúrú tó o gbọdọ mọ

**CVV**
Nọ́ńbà mẹta tó wà lẹyìn káàdì ATM rẹ

**OTP (Ọrọigbaniwọle Akoko Kan)**
Ọrọ àṣírí kan tí wọn máa ń fi ránṣẹ láti àwọn ilé iṣẹ́ fún ìlò ẹekan ṣoṣo. Ó sábà máa ń jẹ nọ́ńbà mẹ́fà tí wọn máa fi ránṣẹ lórí àtẹjíṣẹ ((SMS)

**BVN (Nọmba Ijẹrisi Banki)**
Nọ́ńbà àkànṣe mọkànlá tì wọn máa ń fún gbogbo àwọn tó ń lo báǹkì fún ìdánimọ ní gbogbo báǹkì tí wọn bá ń lò.





## Awọn itanjẹ idoko-owo




Àwọn oníjìbìtì sábà màa ǹ lo ètò ìdókòwò tí kò fẹsẹ múlẹ láti lo gbájúẹ fún àwọn aláìmọkan, kí wọn sì gbé owó wọn sá lọ. Bí ó tilẹ jẹ pé èyí túbọ ń wọpọ sí i, a ní láti wá ọnà tá a lè gbà dáàbò bo ara wa bá a ṣe ń wá owó kún owó.

## Bó o ṣe lè mọ àwọn ìdókòwò oníjìbìtì (investment fraud)

- Wọn ń ṣèlérí pé wà á jẹ èrè rẹpẹtẹ, pé kò séwu rárá
- Ìdókòwò náà kò ní gba àkókò gígùn rárá (Da 50,000 naira kó o sì gba 300,000 naira láàárín ọsẹ méjì)
- Lájòrí ohun tí wọn ń sọ ni pé "gbogbo èèyàn ló ń ṣe é, wọn sì ń rówó gbà."
- Wọn ń kan ẹ lójú pé kó o tètè fowó sí i
- Wọn ò forúkọ sílẹ lábẹ òfin láti ṣe ìdókòwò.













## Bó o ṣe lè dáàbò bo ara rẹ kúrò lọwọ ìdókòwò oníjìbìtì

- Ṣe ìwádìí fínnífínní lórí wọn. Má ṣe jẹ kí àwọn orúkọ ńlá, ọrọ àsọdùn, àti ìrísí pé wọn ń ṣe àṣeyọrí tàn ẹ jẹ. Rí i dájú pé wọn forúkọ sílẹ lábẹ òfin.
- Má ṣe máa lé owó òjijì. Tí ìdókòwò kan bá ń ṣèlérí èrè rẹpẹtẹ láàárín àkókò díẹ, ó yẹ kó o fura.
- Tí ẹnì kan bá gbé ìdókòwò kan wá bá ẹ ṣùgbọn tí kò lè ṣàlàyé ìdì tó fi gbà pé ojúlówó ni, tàbí tó kàn ń sọ pé gbogbo èèyàn ló ń ṣe é, ó yẹ kó o fura.
- Tí ìdókòwò kan bá ń ṣèlérí èrè rẹpẹtẹ láì sí ìsapá kankan (iṣẹ kékeré, owó ńlá), tètè fura.
- Má ṣe jẹ kí wọn tì ẹ gbọn-ọn-gbọn-ọn. Tí onítajà kan bá ń sọ fún ẹ pé kò sí àkókò mọ, pé o ní láti fowó sí ìdókòwò náà nì kíákíá, o yẹ kó o fura. Tó bá jẹ ìdókòwò gidi ni, ó yẹ kí wọn fún ẹ lásìkò láti ronú lórí ẹ kó o tó ṣèpinnu.
- Tó o bá ronú pé ríra ìpín ìdókòwò (shares) mọgbọn dání, pé ojúlówó ni, kọkọ lọ sí orí ìkànnì Nigerian Stock Exchange láti mọ iye tí wọn ń tà á àti ìdíyelé rẹ. Àwọn kan máa ń fẹ kéèyàn ta ìpín ìdókòwò (shares) fún wọn ní iye tó kéré sí ìdíyelé rẹ ní stock exchange.
- Má ṣe fún ẹnikẹni tó bá pè ẹ lórí fóònù tàbí tó fi email ránṣẹ sí ẹ pé òun fẹ fún ẹ nímọràn lórí ìdókòwò tàbí òun fẹ kẹ ẹ jọ dòwò pọ ní ìsọfúnni ẹ èyíkéyìí. Ńṣe ni kó o pa fóònù mọ ọ lẹnu, kó o sì pa email yẹn rẹ.
- Má ṣe kánjú fowó sí ìdókòwò tó o bá lọ sí àwọn ibi ìdálẹkọọ (seminar). Kọkọ ṣe ìwádìí lórí ẹ, kó o sì fọrọ lọ ẹnì kan tó ní ìmọ pípéye lórí irú ìdókòwò bẹẹ.
- Má ṣe yára kó wọ inú ètò ìṣòwò kan nítorí pé wọn fún ẹ ni ǹkan lọfẹẹ.
- Fi ìmọ pípéye àti ìsọfúnni dáàbò bo ara rẹ. Kọ bí o ṣe lè mọ àwọn ètò ìdókòwò oníjìbìtì, kó o sì dáàbò ara rẹ, àwọn mọlẹbí rẹ, àti àwọn ọrẹ rẹ.